**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**AGBÁRA LÁTI ṢE ÌDÁJỌ́**
**OṢÙ KEJÌLÁ, ỌDÚN 2024**
Ìwé Mímọ́ Kíkà: Dáníẹ́lì 3
Ìjẹ́wọ́: Hébérù 10:30

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tó ṣi àwọn òbí mi lọ́nà sínú ìkùnà, o kòní ṣerere lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Ìkùnà àwọn òbí mi kòní jẹyọ nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Sátánì kòní darí ayé mi sínú àwọn iṣẹ́ tíkòwúlò, ní orúkọ Jésù.
8. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, ràmípadà, ní orúkọ Jésù.
9. Mo gbédè, mo sì lé jáde gbogbo agbára tó nfa ogun jíjà àtinúwá, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo aṣọ́bodè òkùnkùn, tó nti àwọn ohunrere sóde fún mi, gba ìyarọ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
11. Mo pàṣẹ kí gbogbo agbára búburú tó n bámi jagun kọ ojú ìjà sí ara wọn, kí wọ́n sì pa ara wọn run, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ẹ̀mí òkùnkùn olùdènà àlàjá, ìdíwọ́ àti apanirun, gba idàrúdàpọ̀, ní orúkọ Jésù.

13. Agbára àti iṣàkóso atòkèwá, gbógunti àwọn ẹ̀mí ipá àti adánilóró, ní orúkọ Jésù.
14. Olúwa, jẹ́ kí ogun abẹ́lé ṣẹlẹ̀ nínú ìjọba òkùnkùn, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo ìtọpinpin búburú ayé mi, gba ìparun nípa iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
16. Ìwọ agbára Ọlọ́run, wọ inú ẹ̀mí, ọkàn àti ara mi lọ, ní orúkọ Jésù.
17. Ìpéjọpọ̀ òkùnkùn tí wọ́n kórajọ lòdì sí ìlọsíwájú mi, yangbẹ nípa àrá iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
18. Mo kọ gbogbo òfin sátánì tí àjogúnbá ṣètò sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo ìpinnu sátánì tí wọ́n ṣe lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi, di asán, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo irúgbìn búburú nínú ẹ̀mí, ọkàn àti ara mi, di fífọ̀ jáde nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
21. Olúwa Ọlọ́run mi, gbémiga nínú ẹ̀mí àti nípa t'ara, ní orúkọ Jésù.
22. Gbogbo àlejò nínú ara mi (iṣẹ́-ìránṣẹ́, ayé àti ìpè), fò jáde, ní orúkọ Jésù.
23. Ọfà sátánì ìyówù tí wọ́n ta sími, padà, ṣàwárí, kí o sì pa ẹni tó rán ọ run, ní orúkọ Jésù.
24. Ẹ̀mí Mímọ́, dìde, kí O sì pa ibùgbé àti àwọn iṣẹ́ ìkà run nínú ayé mi (ilé, ètò-ìṣúná, iṣẹ́-ìránṣẹ́), ní orúkọ Jésù.
25. Gbogbo ẹ̀mí ejò tó n tutọ́ sórí alàjá mi, yangbẹ, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo ọ̀tá àṣepé ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
27. Mo la ọ̀nà mi sínú àwọn alàjá, ní orúkọ Jésù.
28. Mo fagilé gbogbo àṣẹ sátánì lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
29. Mo fagilé gbogbo àṣẹ sátánì lórí ìdílé mi, ní orúkọ Jésù.
30. Mo fagilé gbogbo àṣẹ ibi lórí ìṣerere mi, ní orúkọ Jésù.
31. Mo fagilé àṣẹ sátánì ti iṣẹ́ takun-takun tíkò lérè, ní orúkọ Jésù.
32. Ìwọ agbára àṣetì nínú ayànmọ́ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
33. Àlá ibi, padà sọ́dọ̀ àwọn tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.

34. Ìwọ ọkùnrin alágbára tó n ṣàkóso ìdílé mi, mo sọ ọ́ di aláìlágbára, ní orúkọ Jésù.
35. Ibùkún, ọlá, ìṣerere àti ojúrere, ṣàwárí mi, ní orúkọ Jésù.
36. Mo di egungun ní ọ̀fun ọ̀tá mi, n kò ṣe é gbémìn, ní orúkọ Jésù.
37. Mo fagilé gbogbo òfin búburú tó n ṣàkóso ayé mi, ní orúkọ Jésù.
38. Gbogbo àjẹ́ àti oṣó tọ́wà nídì ọ̀rọ̀ mi, ẹ kòní ní àláfíà ayàfi igbàtí ẹ bá túmisílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
39. Ọlọ́run, fún mi ní agbára láti ní ìgbájúmọ́, ní orúkọ Jésù.
40. Gbogbo ètò láti mú iyàbàrà bá ayé mi nípa ṣẹ̀ ẹ̀ṣẹ̀, kùnà, ní orúkọ Jésù.